# PAULU ATI SILA NINU TUBU

**Işe Awọn Apọsteli 16:9-40**

**ẸKỌ 334 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Awa si mọ̀ pe ohun gbogbo li o nşişẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun, ani fun awọn ẹniti a pè gẹgẹ bi ipinnu rẹ̀" (Romu 8:28).**

**I Ipè Paulu si Makedonia**

1 Ni oju iran, Paulu ri ọkunrin kan ti o wi pe: "Rekọja wá si Makedonia, ki o si ran wa lọwọ," Işe Awọn Apọsteli 16:9

2 Paulu ati Sila wọ ọkọ̀ lọ si Makedonia, wọn si şe isin kan lẹba odò kan, Işe Awọn Apọsteli 16:10-13

3 Lidia şe aajo Paulu ati Sila, Işe Awọn Apọsteli 16:14, 15; I Timoteu 5:10; Heberu 6:10

**II Obinrin Ẹlẹmi Eşu kan Mu Ki Paulu Kẹdun**

1 O mú ère pupọ wá fun oluwa rẹ̀ nipa afọşẹ rẹ̀, Işe Awọn Apọsteli 16:16

2 O tẹle Paulu o si kigbe pe, "Awọn ọkunrin wọnyi ni iranşẹ Ọlọrun Ọgá-ogo", Işe Awọn Apọsteli 16:17

3 Paulu lé ẹmi eşu naa jade kuro ninu rẹ̀, Işe Awọn Apọsteli 16:18

4 Awọn oluwa rẹ̀ binu nitori igbẹkẹle èrè wọn pin, wọn si dawọle Paulu ati Sila lati mú wọn, Işe Awọn Apọsteli 16:19

**III A Lu Wọn a si Fi Wọn si Tubu nipa Aşẹ Awọn Onidajọ**

1 A mú ẹsùn Paulu ati Sila wa si iwaju awọn onidajọ, Işe Awọn Apọsteli 16:20, 21

2 Awọn onidajọ fa aşọ Paulu ati Sila ya wọn si paşẹ pe ki a lù wọ́n, Işe Awọn Apọsteli 16:22, 23

3 A sọ wọn sinu tubu ti inu lọhun, Işe Awọn Apọsteli 16:24

**IV Adura, Iyin, ati Isẹlẹ nla**

1 Isin adura ati orin-iyin bẹrẹ bi o tilẹ jẹ pe a kan àbà mọ́ wọn ni ẹsẹ̀, Işe Awọn Apọsteli 16:25

2 Isẹlẹ nla kan sẹ̀, awọn ilẹkun tubu şi, ìde awọn onde si tú, Işe Awọn Apọsteli 16:26

3 Onitubu gbiyanju lati pa ara rẹ̀ şugbọn Paulu dá a lẹkun, Işe Awọn Apọsteli 16:27, 28

4 Onitubu ati ara ile rẹ̀ ri igbala, a si şe itọju awọn onde naa, Işe Awọn Apọsteli 16:29-40

## ALAYE

### Irin-Ajo Paulu Ẹẹkeji

Ni akoko ẹkọ wa yii, Paulu wà lori irin-ajo rẹ̀ keji. O ti bẹ ọ̀pọlọpọ ilu wò nibi ti oun ati Barnaba ti waasu Ihinrere ti wọn si ti dá ijọ silẹ ni irin-ajo wọn ekinni. Barnaba kò bá Paulu lọ ni igba keji yii, şugbọn o lọ si Kipru ilu rẹ̀. Paulu mú Sila lọ gẹgẹ bi alabaşişẹpọ rẹ̀. Lẹyin ti o si ti bẹ awọn ilu ti wọn dé ni işaaju wò tán, o lọ si Siria ati Kilikia o n fi ẹsẹ̀ ijọ mulẹ. Lẹyin naa awọn mejeeji lọ si iha ariwa ati iwọ-oorun si Galatia ati Misia. Paulu ti pinnu lati lọ si iha oke si ilu Bitinia, şugbọn Ẹmi Oluwa kọ̀ fún un, nitori naa wọn lọ si Troasi, nibẹ ni Paulu ti ri iran ti o dari rẹ̀ kuro ni Asia lọ si Europe.

### Ipè Lati Makedonia

Nigba meji ọtọọtọ ni Ẹmi Ọlọrun kọ̀ fun Paulu lati tẹ̀ siwaju lọ si Asia, boya o wá si Troasi ti o si n woye ninu ọkan rẹ̀ ibi gan an ti Oluwa fẹ́ ki oun lọ. Şugbọn Ọlọrun kò fi i silẹ ninu iyemeji pẹ́ titi. O ri iran kan ni oru; ọkunrin kan ara Makedonia duro, o si n bẹ̀ ẹ wi pe, "Rekọja wá si Makedonia, ki o si ran wa lọwọ." Oluwa mọ̀ pé ọpọlọpọ ọkàn ni o wa ni ilu Griki ti wọn şe tán lati gba Ihinrere. Lati igbaani titi di isisiyi ni ipe "Makedonia" ti n dún ni eti igbọ́ ọ̀pọlọpọ awọn iranşẹ Ọlọrun lati rú ifẹ wọn soke.

O daju pe Ẹmi Mimọ́ ni o n tọ́ iṣisẹ awọn ojiṣẹ Ọlọrun wọnyi lọ si Europe. Eyi ṣẹlẹ ni nnkan bi ẹgbaa ọdun sẹyin, sibẹsibẹ Ẹmi Mimọ́ kò tii dẹkun lati maa tọ́ iṣisẹ awọn iranṣẹ Ọlọrun tootọ ati awọn alakoso lode oni.

Saa miiran fẹrẹ bẹrẹ ninu iṣẹ-iranṣẹ Paulu. Ipè ti o jade lati Makedonia wá yii fi hàn pe ogunlọgọ ọkàn ni ilu naa ni oungbẹ Ọrọ̀ Ọlọrun n gbẹ, ọkàn wọn si ṣe tán lati gba Ihinrere.

**Awọn Onigbagbọ́ Kin-in-ni ni Ilẹ Awọn Alawọ funfun**

Awọn iranṣẹ Ọlọrun kin-in-ni si ilẹ awọn alawọ funfun mú irin-ajo wọn pọ̀n lọ si ilu Filippi ti i ṣe olu-ilu awọn ilu ti ó wà ni iha ihin yii. Lai si aniani, awọn Ju kò pọ̀ nibẹ. Ṣugbọ̀n ni Ọjọ Isinmi kin-in-ni, Paulu ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ wà lẹyin odi ilu lẹba odo kan nibi ti awọn eniyan ti maa n gbadura. Nibẹ ni awọn obinrin diẹ pejọ pọ si; diẹ ninu wọn jẹ́ Ju awọn diẹ si jẹ́ alawọṣe Ju.

Paulu ati Sila joko wọn si bá awọn obinrin naa sọrọ. Gẹgẹ bi ibi ti wọn gbe wà yii ti ri, o daju pe isin ránpẹ lasan ni wọn ṣe, ṣugbọn obinrin kan wà nibẹ ti ebi Ọrọ Ọlọrun n pa. O ṣi ọkàn rẹ̀ payá si otitọ. Oun ni ẹni kin-in-ni ti o kọ gba Ihinrere lẹyin ti Paulu gbọ́ ipè ti o jade si i ni Makedonia. Oun ati awọn ara ile rẹ tẹwọ gba Ihinrere Majẹmu Titun. O ni lati jẹ́ pé Paulu mẹnu ba ẹkọ iribọmi ninu iwaasu rẹ̀ ni owurọ ọjọ naa nitori ti a ṣe iribọmi fun Lidia ati awọn ara ile rẹ̀. Lẹsẹkẹsẹ ni Lidia pinnu pé awọn iranṣẹ Ọlọrun wọnyi ni lati wọ̀ si inu ile oun. O rọ̀ wọ́n to bẹẹ ti wọn fi gbà lati wọ̀ sibẹ. O fi tọkàntọkàn gba Ihinrere, o si n mu ofin ifẹ ti Jesu kede rẹ̀ ṣẹ -- ifẹ si awọn iranṣẹ Ọlọrun ati awọn eniyan Rẹ̀ -- o si n to iṣura ipilẹ rere jọ fun ara rẹ̀ di igbà ti n bọ̀ (1 Timoteu 6:19). Bibeli sọ bayii pé: “Ẹ máṣe gbagbé lati mã ṣe alejò; nitoripe nipa bẽ li awọn ẹlomiran ṣe awọn angẹli li alejò laimọ̀” (Heberu 13:2).

**Awọn Inunibini**

Iṣẹ awọn iranṣẹ Ọlọrun yii kò le maa lọ geere bẹẹ lai si idojukọ. Eṣu gbọ́n ninu ọgbọ́n arekereke rẹ̀ bi o ti n sa ipa rẹ̀ lati bi iṣẹ Oluwa wó. Nigba pupọ a maa fi èké pamọ́ sabẹ otitọ lati fi tan ọmọ-eniyan jẹ. Ọdọmọbinrin kan bẹrẹ si i tẹle Paulu ati Sila, o si n kigbe wi pe, “Awọn ọkunrin wọnyi ni iranṣẹ Ọlọrun Ọgá-ogo, ti nkede ọ̀na igbala fun nyin” (Iṣe Awọn Apọsteli 16:17). Otitọ ni o n sọ, ṣugbọn ẹri ẹlẹmi eṣu kò le mu ẹnikẹni duro. Eṣu ni o n gba ẹnu rẹ̀ sọrọ, lai si aniani, ohun ti o fẹ ṣe ni pe ki o pokiki Apọsteli Paulu ati ẹlẹgbẹ rẹ̀ lati gbé wọn lé ayé lọwọ ki o ba le gba ọna yii ṣe idena iṣẹ ti Ọlọrun n ti ọwọ wọn ṣe. Ọna ti o gbà sọ ọ́ ni o mu ki inu Paulu bajẹ. Iru ẹmi kan naa ni o wà ninu ẹlẹmi eṣu ara Gadara nì nigba ti o ri Jesu.

Ofin paṣẹ pe: “Máṣe yipada tọ̀ awọn ti o ni imọ afọṣẹ, bẽni ki o má si ṣe wá ajẹ́ kiri, lati fi wọn bà ara nyin jẹ́: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin” (Lefitiku 19:31). Ọlọrun kọ̀ fun ni lati ni ohunkohun lati ṣe pẹlu awọn ti n bá iwin gbimọ pọ̀, ẹmi abokulo, tabi awọn alafọṣẹ. Ọlọrun korira rẹ̀, nitori pe lati ọdọ eṣu ni o ti wá. Ẹṣẹ̀ ni fun ẹnikẹni lati lọ wadii ohun wọnni ti Ọlọrun kò fi aṣiiri rẹ̀ hàn fun ni, lọdọ awọn alafọṣẹ tabi abokulo; iwa bẹẹ jẹ́ abuku si ọgbọ́n Ọlọrun. Ninu aanu nla Rẹ̀, Ọlọrun fi pupọ ninu ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ ọla pamọ fun ẹda, O si fi ireti dipo rẹ̀.

Paulu lé ẹmi aimọ́ naa jade kuro lara obinrin naa, eyi si fa ibinu awọn oluwa rẹ̀. Ọna lati maa mu u lo lati ri owó gbà nipa afọṣẹ rẹ̀ dopin. Nitori naa wọn mú Paulu ati Sila lọ siwaju awọn onidajọ. Awọn onidajọ gbọ́ ẹsun ti a kà si Paulu ati Sila lọrun, ṣugbọn wọn kò ṣe iwadii ọ̀rọ lẹnu wọn -- eyi lodi si àṣà ilẹ Romu. Lẹyin ti wọn ti lù wọ́n pupọ, wọ́n sọ wọ́n sinu tubu, wọn si tẹẹ mọ́ awọn onitubu leti lati pa wọ́n mọ́ daradara; onitubu pẹlu si sọ awọn eniyan Ọlọrun wọnyi sinu tubu ti inu lọhun, o si kan àbà mọ́ wọn li ẹsẹ̀.

**Adura ati Isin Ọpẹ**

Ki i ṣe ohun ti o rọrun lati maa kọrin nigba ti idanwo wa bá dé ogogoro. Nigba pupọ a da bi ẹnipe ẹrù naa wuwo ju eyi ti ẹnikan le rù lọ. Ṣugbọn Jesu ti ṣeleri pe Oun yoo bá wa gbé ẹrù wúwo wa. Paulu ati Sila gbadura, wọn si kó aniyan wọn le Ọlọrun lọwọ nitori ti O wi pe, “Emi kò jẹ fi ọ silẹ, bẹni emi kò jẹ kọ ọ silẹ.” Bi wọn ti n gbadura, ayọ kun ọkàn wọn to bẹẹ ti wọn bẹrẹ si kọ orin iyin si Ọlọrun.

Awọn onde iyoku gbọ́ orin ayọ wọn. Wò bi ẹnu yoo ti ya awọn onde tó nigba ti wọn taji ti wọn si n gbọ́ adura ati orin lẹnu awọn ti a fi abà si lẹsẹ lẹyin ti a ti lú wọ́n ni ilukilu ti ara wọn si n ṣẹjẹ. Kò ni

jẹ́ ohun iyanu fun awọn onde bi wọn ba gbọ iro gbingbin ati èpè kikankikan, ṣugbọn adura ati orin kikọ jẹ́ ohun ti wọn kò ni ìreti lati gbọ́. Adura ati orin iyin mú ki Ọrun paapaa boju wolẹ, ki O si tẹti si wọn. Lojiji isẹlẹ nla sẹ̀, ipilẹ ile tubu naa si mì tìtì. Lọgan gbogbo ilẹkun ṣi silẹ, ide olukuluku onde si tú. Irú eyi kò ṣẹlẹ ri ni ile tubu ni ilu Filippi. Agbára Ọlọrun pọ to bẹẹ ti kò si ọ̀kan ninu awọn onde ti o gbiyanju lati salọ.

**Igbala Onitubu**

Isẹlẹ naa ta onitubu ji, lẹsẹkẹsẹ ó fò dide lori akete rẹ̀, o ri i pe awọn ilẹkun ile tubu ṣi silẹ. "Gẹgẹ bi ofin ilẹ Romu, onitubu ti arufin ba sa mọ lọwọ nipa ilọra, yoo ru iya ti awọn arufin naa ni lati jẹ." Nigba pupọ ni awọn onitubu yoo pa ara wọn kaka ki a pa wọn lati ọwọ́ awọn alaṣẹ. Ni ireti pe awọn onde wọnyi ti salọ, onitubu yii fa idà yọ lati pa ara rẹ. Bi o tilẹ jẹ́ òru ọganjọ ni, ti okunkun si bolẹ, imọlẹ diẹdiẹ ti n wọle lati ẹnu ọ̀na ti o ṣi silẹ mú ki Paulu ri ohun ti onitubu naa fẹ ṣe, o si kọ kàrá si i wi pe, "Máṣe pa ara rẹ lara: nitori gbogbo wa mbẹ nihinyi."

Idalẹbi wọ inu ọkàn onitubu. Ọkàn rẹ̀ n fẹ́ irú igbala ti Paulu ati Sila ni. O beere iná, pẹlu iwariri o wolẹ niwaju awọn eniyan Ọlọrun. Nigba naa ni o mú Paulu ati Sila jade o si wi pe, "Alàgba, kini ki emi ki o ṣe ki ng le là?" Paulu kò ni ṣalai ranti wàyii igba ti oun paapaa n ṣe inunibini si awọn Onigbagbọ́. Oluwa mú Paulu ni ọna ajo rẹ̀ si Damasku o si kigbe wi pe, "Oluwa, kini iwọ nfẹ ki emi ki o ṣe?" (Iṣe Awọn Apọsteli 9:6).

Idahun Paulu si ibeere onitubu naa kò le: "Gbà Jesu Kristi Oluwa gbọ́, a o si gbà ọ là, iwọ ati awọn ará ile rẹ pẹlu." Ọkan onitubu yii gbọgbẹ gidigidi nitori ẹ̀ṣẹ ti o ti n dá, ọkàn rẹ̀ si wà ni ipò ti o fi le gbagbọ lati odo ọkàn rẹ̀. Igbagbọ́ atọkànwa -- igbagbọ ti o lọ pẹlu igbọran si gbogbo aṣẹ Ọlọrun – eyi ni o n fun ni ni iriri atunbi. Ogunlọgọ eniyan ni o n fi ọgbọ́n ori gba otitọ Ọrọ Ọlọrun gbọ́ ti wọn si n lero pe wọn ti ri igbala, ṣugbọn eyi nikan kò le mu ìbí titun wa. Ọrọ Ọlọrun sọ pe, "Bi iwọ ba fi ẹnu rẹ jẹwọ Jesu li Oluwa, ti iwọ si gbagbọ́ li ọkàn rẹ pe, Ọlọrun ji i dide kuro ninu okú, a o gbà ọ là. Nitori ọkàn li a fi igbagbọ́ si ododo; ẹnu li a si fi ijẹwọ si igbala " (Romu 10:9, 10).

Alẹ ọjọ yii kò ṣee gbagbe! Lakọkọ ipade adura, lẹyin naa orin, isẹlẹ, igbala onitubu ati awọn ara ile rẹ, wiwẹ ọgbẹ́ Paulu ati Sila, isin iribọmi, lopin rẹ̀, àse nla nibi ti olukuluku n yọ̀ ti wọn si n yin Ọlọrun logo fun igbala nla Rẹ̀.

Eyi ni ogun kin-in-ni nipa ti ẹmi ati iṣẹgun kin-in-ni ti awọn ojiṣẹ Ọlọrun meji, ti ijọ akọkọbẹ̀rẹ wọnyi ni fun Ọlọrun lori ilẹ awọn alawọ funfun. Ilẹ awọn alawọ funfun di papa ogun laaarin agbára Satani ati agbára Kristi. Ogun naa si n lọ lọwọlọwọ, ṣugbọn ọjọ́ kan n bọ̀ nigba ti gbogbo awọn ajẹriku yoo duro ni iṣẹgun lori ilẹ yii lati gbé asia Jesu Kristi ọba wọn soke. Ọjọ́ Ologo!

Ni ọdun mẹwaa lẹyin eyi, Paulu kọ Episteli si awọn ara Filippi, nibi ti o gbé sọ nipa irú ifẹ nla ti o ni si Lidia ati awọn ará ile rẹ̀, ati fun onitubu nì ati awọn ara ile rẹ̀ ati fun gbogbo awọn ti a gbala ni Filippi. Ohun ti o sọ ni eyi:

**"Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun mi fun gbogbo iranti nyin ti mo nṣe,**

**Nigbagbogbo ninu gbogbo adura mi fun nyin li emi nfi ayọ̀ bẹ̀bẹ,**

**Nitori idapọ nyin ninu ihinrere lati ọjọ ekini wá titi fi di isisiyi;**

**Ohun kan yi sa da mi loju, pe ẹniti o ti bẹ̀rẹ iṣẹ rere ninu nyin, yio ṣe aṣepe rẹ̀ titi fi di ọjọ Jesu Kristi:**

**Gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati rò eyi fun gbogbo nyin, nitoriti ọkàn nyin wà lọdọ mi, niwọn bi o ti ṣepe gbogbo nyin ni iṣe alabapin ore-ọfẹ pẹlu mi ninu idè mi ati ninu idahùn-ẹjọ mi ati ifẹsẹmulẹ ihinrere.**

**Nitori Ọlọrun li ẹlẹri mi, bi mo ti nṣafẹri nyin to gidigidi ninu iyọ́nu Jesu Kristi."**

**"Nitorina, ẹnyin ará mi olufẹ, ti mo si nṣafẹri gidigidi, ayọ̀ ati ade mi, ẹ duro ṣinṣin bẹ̃ ninu Oluwa, ẹnyin olufẹ mi" (Filippi 1:3-8; 4:1).**

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni a n pè ni ipè Makedonia?
2 Nibo ni a ti kọ́ waasu Ihinrere ni ilẹ awọn alawọ funfun?
3 Ta ni alawọ funfun kin-in-ni ti o di Onigbagbọ́?
4 Ki ni ṣe ti wọn fi gbé Paulu ati Sila jù sinu tubu?
5 Ki ni Bibeli sọ nipa afọṣẹ?
6 Ta ni o fun awọn abokulo ni agbára wọn?
7 Sọ bi onitubu nì ṣe ri igbala.
8 Ki ni iṣẹ ti awọn onidajọ rán si Paulu ati Sila ni ọjọ́ keji?
9 Ki ni idahun Paulu si iṣẹ onidajọ?
10 Darukọ nnkan mẹjọ pataki ti o ṣẹlẹ loru nigba ti Paulu ati Sila wa ninu tubu.